# ẸWU ATI AṢỌ IGUNWA AWỌN ALUFAA ISRAẸLI

## Ẹksodu 28:1-43; 29:29, 30; 39:1-31

### ẸKỌ 97 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Emi o yọ̀ gidigidi ninu OLUWA, …. nitori o ti fi agbáda wọ̀ mi" (Isaiah 61:10).**

### Ọlọrun Maa N Fiyesi Eto Kinnikinni

Nigba ti Ọlọrun fi ilana iṣẹ alufaa lelẹ nigba ti a gbé Agọ kalẹ ni iju, ki i ṣe kiki awọn iṣẹ ti Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ ni lati ṣe nikan ni Ọlọrun sọ fun Mose, ṣugbọn O sọ aṣọ ti wọn gbọdọ wọ fun un pẹlu. A ri i pe Ọlọrun fiyesi i gidigidi pe ki a ṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi ọrọ Rẹ̀ gan an. Bakan naa ni o ṣe pataki fun wa ni akoko yii lati tẹle awọn ẹkọ Bibeli ni kinnikinni.

Aṣọ Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ ni lati jẹ aṣọ mimọ́, ko si si ẹlomiran ti o gbọdọ wọ iru aṣọ ti wọn. A fi agbada ẹ̀ṣọ́ kan wọ awọn ọmọ Ọlọrun lode oni, eyi ti awọn eniyan aye yii ko le fi ara wé: "O fi agbáda wọ̀ mi, O ri fi aṣọ ododo bò mi" (Isaiah 61:10).

Ọlọrun ni ero kan lọkàn fun gbogbo ọ̀ṣọ́ ẹwu ti awọn alufaa n wọ̀. Wọn jẹ́ aworan oore-ọfẹ ti inu tí awọn eniyan mimọ Ọlọrun ni. Wọn ni lati jẹ ti aṣọ ọgbọ wiwẹ́, Johannu si sọ fun wa ninu Ifihan pe aṣọ ọgbọ wiwẹ́ yii ni ododo awọn eniyan mimọ́. Ẹwu wọn ni lati jẹ eyi ti o wà fun "ogo ati ọṣọ́." Nigba ti Peteru sọrọ nipa ọ̀ṣọ́ awọn ọmọ Ọlọrun, o wi pe, "Ọṣọ́ ẹniti ki o má jẹ ọṣọ́ ode. . . . . ṣugbọn ki o jẹ ti ẹniti o farasin li ọkàn.ti ẹmí irẹlẹ ati ẹmí tutù, eyiti iṣe iyebiye niwaju Ọlọrun" (1 Peteru 3:3, 4).

### Aṣọ Igunwa Olori Alufaa

Aṣọ igunwa olori alufaa tilẹ tun jẹ eyi ti ẹwa rẹ pọ pupọ ju ti awọn alufaa iyoku lọ. O ni iṣẹ ti o jẹ mimọ́ ju ti awọn iyoku lọ lati ṣe fun Oluwa, iwa mimọ́ ti rẹ̀ ni lati pọ ju ti awọn iyoku lọ. Ni ori rẹ̀ ni yoo dé fila kan. Aṣọ ọgbọ wiwẹ ni a fi ṣe e, yoo si fi we ori rẹ̀ bi láwani. Ni iwaju rẹ ni awo wura kan wa lara eyi ti a kọ ọrọ wọnyii sí, MIMỌ́ SI OLUWA. Nigbakigba ti awọn eniyan naa ba wo olori alufaa, ti wọn si ri awo wura yii, wọn o ronu nipa iwa mimọ́ Ọlọrun.

Bi iṣẹ ti Ọlọrun pe wa lati ṣe ba ti tobi to, bẹẹ ni a gbọdọ gbadura ju bẹẹ lọ to, ki a si ṣe ifararubọ ti o pọ si i ki a ba le ni ẹmi ni ninu wa lati ṣe wa lọṣọ fun iṣẹ naa. Ẹwu aṣọ ọgbọ wiwẹ ti olori alufa n wọ̀ yii ni a fi owu alawọ wura ati alawọ didan daradara miiran ṣe iṣẹ ọna pupọ si lara. Aṣọ igunwa rẹ̀ ko ni apa, o si kanlẹ titi o fẹrẹ de ọrun ẹsẹ rẹ̀. Ni ayika eti rẹ̀ nisalẹ ni ọpọlọpọ agogo wura kékèké wà, a si ṣe iṣẹ abẹrẹ daradara si afo ti o wa laaarin awọn agogo naa. Ko si ẹni ti o gbọdọ wọ inu Agọ naa bi ko ṣe kiki awọn alufaa, nitori naa didún ti awọn agogo wura wọnni n dún lara aṣọ olori alufaa nigba ti o ba n rin nibẹ a mu ki awọn eniyan lode mọ pe o wà laaye ati pe o n bẹbẹ fun wọn niwaju Ọlọrun.

Olori alufa a maa wọ ẹwù efodi "ti wurà, ti aṣọ-alaró, ati elesè-àluko, ti ododó, ati ọ̀gbọ olokùn wiwẹ iṣẹ ọlọnà" sori aṣọ igunwa rẹ̀. Apa kan rẹ̀ ṣẹ́ bo ejika rẹ̀ lẹyin, apa keji si ṣẹ́ bo aya rẹ̀. A fi ide de e mọlẹ ni ejika mejeeji; lori ejika kọọkan ni okuta ónikì kọọkan wà, a si fín orukọ awọn ẹya Israẹli mẹfa sori ekinni ati orukọ awọn ẹya mẹfa iyoku sori ekeji. Awọn Ọmọ Israẹli ko le wọle lọ siwaju Ọlọrun tikara wọn, ṣugbọn olori alufaa a maa ru orukọ wọn lọ lori ejika rẹ̀ nigba ti o ba wọ Ibi Mimọ́ lọ.

### Igbaya

Olori alufaa a si tun maa ru orukọ awọn Ọmọ Israẹli lori aya rẹ̀ niwaju Oluwa gẹgẹ bi igbaya ti a to okuta mejila sí. Okuta kọọkan yatọ si ara wọn, lori ọkọọkan ni a si kọ orukọ awọn ẹya Israẹli kọọkan si. Olori alufaa nikan ni o n wọ efodi pẹlu igbaya ti o ṣe iyebiye yii, nitori naa a ri i pe Israẹli ni lati gbẹkẹ le olori alufaa nikan, fun ẹbẹ niwaju Ọlọrun. Nihin lẹẹkan si i ni a ri olori alufaa ti o jẹ́ apẹẹrẹ Jesu. Jesu ti lọ si Ọrun lati maa bẹbẹ niwaju Ọlọrun fun awọn eniyan Rẹ̀ ti o wà ni ayé.

Eyi ti o ṣe pataki ju lọ ninu gbogbo iwọṣọ olori alufaa ni Urimu ati Tummimu. Nipasẹ awọn wọnyii ni awọn alufaa fi n mọ ohun ti i ṣe ifẹ Ọlọrun. Kò si ẹni ti o mọ bi wọn ti ri gan an, ṣugbọn Ọlọrun sọ fun Mose pe: "Iwọ o si fi Urimu on Tummimu sinu igbàiya idajọ; nwọn o si wà li àiya Aarọni, nigbati o ba nwọle lọ niwaju OLUWA; Aarọni yio si ma rù idajọ awọn ọmọ Israẹli li àiya rẹ̀ nigbagbogbo niwaju OLUWA" (Ẹksodu 28:30).

Ọlọrun ko ba awọn alufaa sọ̀rọ gẹgẹ bi O ti ṣe pẹlu Mose "li ojukoju." Wọn ni lati gbẹkẹ le Urimu ati Tumimu lati mọ ifẹ Ọlọrun. Ọpọlọpọ ọdun lẹyin eyi, ni akoko Dafidi, nigba ti apoti ẹri ko si ninu Agọ, lọna bayii ni wọn fi n mọ ifẹ Ọlọrun sibẹ. Dafidi mọ̀ pe Saulu n wá ọna lati pa oun, o si fẹ mọ ohun ti Ọlọrun n fẹ ki oun ṣe. Nitori naa o pe Abiatari alufaa lati mu efodi wa ki oun ba le beere lọwọ Oluwa. Ọlọrun si da a lohun nipasẹ Urimu ati Tummimu (1 Samueli 23).

Awọn eniyan gbagbọ pe ni ọna bayii ni awọn Ọmọ Israẹli fi maa n mọ ẹya naa ti yoo kọkọ lọ lati bá awọn ara Kenaani jà, gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ ninu Awọn Onidajọ 1:1, 2; a si kà ninu Awọn Onidajọ 20:18 pe: “Awọn ọmọ Israẹli si dide, wọn si lọ si Beti-eli, nwọn si bère lọdọ Ọlọrun, wipe, Tani ninu wa ti yio tètekọ gòke lọ ibá awọn ọmọ Benjamini jà? OLUWA si wipe, Juda ni yio tète gòke lọ.” Ṣugbọn nigba kan nigba ti Saulu beere lọdọ Ọlọrun lẹyin ti o ti dẹṣẹ, kò si idahun, “nipa alá, nipa Urimu tabi nipa awọn woli” (1 Samueli 28:6).

Ohunkohun yowu ki Urimu ati Tummimu jẹ́, wọn a maa sọ ifẹ Ọlọrun di mimọ̀, wọn a si maa fun olori alufaa ni ọgbọ́n lati ṣe idajọ awọn eniyan. Idajọ Ọlọrun ki i ṣe “nipa ìri oju rẹ̀, bẽni ki yio dajọ nipa gbigbọ́ eti rẹ̀” (Isaiah 11:3). Oun a maa wo ọkàn, Oun si mọ̀ bi awọn eniyan ba n sọ otitọ ni tabi wọn n purọ. Olori alufaa jẹ́ onidajọ laaarin awọn eniyan naa, ṣugbọn sibẹ o ni lati beere ọgbọ́n lọdọ Oluwa.

**Ipa Ti Wa Ninu Ẹbẹ**

Oluwa ti yàn lati fi ẹwa iwa mimọ wọ awọn ọmọ Rẹ̀ laṣọ. O ti fi ọ̀ṣọ́ ti ẹmi ṣe wa lọṣọ, O ti fi agbada ti o niyin bò wa. Nigba ti alufaa ba wọ ibi mimọ ti o lẹwa nì lọ, nibi ti a fi aṣọ ọ̀gbọ̀ wiwẹ ati wura ti o jẹ́ mimọ ju lọ ṣe lọṣọ lati fi ọ̀wọ fun Ibi Mimọ́ Ọlọrun hàn a ni lati fi agbada mimọ wọ̀ ọ, ki o ba le yẹ lati ṣe iṣẹ isin niwaju Oluwa. Bawo ni eniyan ṣe le dan an wo nigba naa lati ṣiṣẹ fun Oluwa pẹlu agbada eleeri, aṣọ igunwa ti ẹ̀ṣẹ ti bajẹ? Bi eniyan ba jẹ ẹlẹṣẹ ko ni ẹtọ lati ṣe ohunkohun ninu iṣẹ isin Ọlọrun. Ohun ti o le ṣe ni lati gbadura irẹlẹ pẹlu ironupiwada, “Ọlọrun, ṣãnu fun mi, emi ẹlẹṣẹ.” Ọlọrun yoo gbọ́ iru adura bẹẹ ti o ti inu ọkàn wá, yoo si wẹ gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ nu, a si sọ ọ di Onigbagbọ, ẹni ti agbada rẹ̀ mọ́.

Nigba ti a ba sọ wa di mimọ́, a fi Ẹmi Ọlọrun ti o pọ ju ti akọkọ lọ ṣe wa lọṣọ eyi ti i maa mu ki a ni ẹwa iwa mimọ nì. Ọlọrun ti fi ibukun ti ẹmi bukun fun wa, O si n reti pe ki a ṣe ohun kan fun Oun. A ni lati gbe ẹru awọn arakunrin wa ninu ọkàn wa wá siwaju Ọlọrun ninu adura. Bi wọn ba n ṣaisan a o ni ki Ọlọrun wo wọn san; bi wọn ba n yọ, ki a ba wọn yọ̀; ninu ibanujẹ wọn, ki a ba wọn sọkun ki a si gbadura pe ki Ọlọrun ràn wọn lọwọ lati ba wọn gbe ẹru wọn. Ki o ma jẹ kiki iwuwo adura fun awọn ẹbi wa (awọn ti a fẹran pupọ ju lọ), nikan ni a o rù ninu ọkàn wa, ṣugbọn ti gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun. “Ẹ si mã gbadura fun ara nyin. . . . . . Iṣẹ ti adura olododo nṣẹ li agbara pupọ” (Jakọbu 5:16).

**Mimọran**

Nigba ti Ẹmi Mimọ ba wọ inu ọkàn wa ti a si fi Ẹmi Mimọ wọ̀ wa, A maa fun wa ni oye lati mọ eke yatọ si otitọ. Nigba ti a ba ri igbala a o ni imọran yii niwọn, ati ju bẹẹ lọ nigba ti a ba ni isọdimimọ. Ṣugbọn bi a ti n ba Ọlọrun rìn timọtimọ si i lẹyin ti a ba ti ri Ẹmi Mimọ́ gbà, yoo maa fun wa ni oye ti o gbòorò ju bẹẹ lọ. A ni lati gbadura pupọ pe ki O kọ wa ni ifẹ Rẹ̀.

A ko fẹ lati dá arakunrin wa lẹjọ; Jesu ni Ẹni ti o n ṣe idajọ. Ṣugbọn a ki yoo gba ohun ti o lodi gbọ́ tabi ki a fi ara mọ́ ohun ti Ọlọrun korira. Ẹmi Rẹ̀ a maa kọ́ wa ni ohun ti i ṣe otitọ, a si maa tọ́ wa ni ọna ododo ati iwa mimọ́ tootọ. A le mọ̀ nigba ti Ẹmi Mimọ ba n tọ wa ti ki i ṣe ẹmi ti ọta nì, nitori Ẹmi Ọlọrun ati Ọrọ Ọlọrun a maa fohùn ṣọ̀kan.

Ẹ jẹ ki a gbe igbesi-ayé wa nigba gbogbo ni ọna ti Ọlọrun yoo fi maa da wa lohùn nipa Ẹmi Rẹ̀ gẹgẹ bi awọn alufaa igba nì ti maa n mọ ifẹ Ọlọrun nipasẹ Urimu ati Tummimu.

**AWỌN IBEERE**

1. Ṣe apejuwe ẹwu awọn alufaa.
2. Ki ni a kọ sara awo wura ti o wa lara fila?
3. Ki ni aṣọ ọ̀gbọ̀ funfun n ṣe apẹẹrẹ rẹ̀?
4. Ki ni ọ̀ṣọ́ ti ẹmi ti eniyan gbọdọ ni ki o to yẹ lati ṣiṣẹ fun Oluwa?
5. Ki ni Urimu ati Tummimu jẹ́?
6. Ki ni Urimu ati Tummimu ti wa?